# IYỌNU MEJE IKẸYIN

## Ifihan 15:1-8;16:1-21

## ẸKỌ 463 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Bi kò si ṣepe a ké ọjọ wọnni kuru, kò si ẹda ti iba le là a; ṣugbọn nitori awọn ayanfẹ li a o fi ké ọjọ wọnni kuru" (Matteu 24:22).**

**I Iran Johannu Ni Ti Awọn Aṣẹgun Ni Ọrun**

1 Johannu ri awọn ti wọn "ti ṣẹgun ẹranko na," Ifihan 15:2;13:4, 8;Romu 8:35-37
2 Wọn n kọ orin ti Mose, ati orin ti Ọdọ-Agutan naa, Ifihan 15:3; 14:3; Ẹksodu 15:1
3 Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun ni yoo tẹle itujade idajọ Ọlọrun ikẹyin sori ayé, Ifihan 15:4

**II Ipalẹmọ Fun Itujade Iyọnu Meje Ikẹyin**

1 Johannu ri Tẹmpili ti a ṣi silẹ ni Ọrun, Ifihan 15:5
2 Awọn angẹli meje gba igo ti o kún fún iyọnu meje ikẹyin, Ifihan 15:1, 6-8; Ẹksodu 40:34, 35

**III Itujade Igo Marun-un Ti O Kun Fun Ibinu Ọlọrun Sori Ayé**

1. A paṣẹ fun awọn angẹli naa lati "lọ", Ifihan 16:1
2. A tú igo kin-in-ni jade, Ifihan 16:2; Ẹksodu 9:9-11
3. A tú igo keji jade, Ifihan 16:3; Ẹksodu 7:17; Ifihan 8:8, 9
4 A tú igo kẹta jade, Ifihan 16:4-7; 8:10, 11; 18:24; Matteu 23:34, 35
5 A tú igo kẹrin jade, Ifihan 16:8, 9
6 A tú igo karun-un jade, Ifihan 16:10, 11

**IV Itujade Igo Kẹfa Ati Isunmọtosi Har-magẹddoni**

1 A ṣe imurasilẹ de Har-magẹddoni, Ifihan 16:12-14
2 A tẹgun fun "ogun ọjọ nla Ọlọrun Olodumare", Ifihan 16:14, 16;17:14; 19:17-21; Joẹli 3:1, 2
3 Kristi dé sori ayé lati ja ijà nla ikẹyin yii, Ifihan 16:15; 1:7; 2 Tẹssalonika 2:8

**V Itujade Igo Keje**

1 A dé opin ibinu Ọlọrun, Ifihan 16:17
2 "Manamana si kọ, a si gbọ́ ohùn, ãrá si san, ìsẹlẹ nla si sẹ̀", Ifihan 16:18;Matteu 24:29; Isaiah 29:6; 2:19-21
3 A sọ asọtẹlẹ iṣubu Babiloni, Ifihan 16:19;14:8; 18:5
4 A sọ ti jijabọ́ yinyin nla, sibẹ naa awọn eniyan ṣi n sọrọ odi si Ọlọrun, Ifihan 16:21;11:19; Ẹksodu 19:23-25

## ALAYE

Igba ipọnju ati wahala kan n bọ̀, eyi ti o ba ni lẹru lati ronu nipa rẹ̀. A o fi ibinu Ọlọrun bẹ ayé yii wò nitori ikọ̀silẹ aanu ti Ọlọrun ti n nawọ rẹ̀ lati ayebaye. Ni akoko ti o kù si dẹ̀dẹ yii, a o tú ibinu Ọlọrun jade lai dẹkun. A o tilẹ fun awọn eniyan ni ẹjẹ lati mu, nitori "eyiyi li o yẹ wọn." Ero yii ti ba ni lẹru to! Ede eniyan ko le ṣapejuwe iṣẹlẹ buburu ti yoo ṣẹlẹ nihin lori ilẹ ayé ni akoko Ipọnju Nla naa. A n gbiyanju lati fi oju ẹmi wo bi yoo ti ri nipa lilo imọ gẹgẹ bi ọrọ Ọlọrun ti sọ fun wa, sibẹ o daju pe iba diẹ ṣinun ni ọkàn wa le dimu nipa ẹru ti yoo jẹ ipin awọn ti yoo wà ninu ayé ni akoko yii.

**"Bi Ikẹkun"**

Awa mọ̀ pe idajọ wọnyii n bọ̀ ṣugbọn awọn eniyan ayé kò mọ̀. A n ka Bibeli a si mọ̀ pe gbogbo asọtẹlẹ Iwe naa yoo ṣẹ. Ṣugbọn o ṣe e ṣe lati maa gbọ́ iwaasu ati lati maa ka isọtẹlẹ sibẹ ki a má "mọ̀". Gẹgẹ bi o ti ri ni ọjọ Noa – o n waasu bi o ti n kan ọkọ̀, ṣugbọn bi o tilẹ jẹ pe awọn eniyan naa n gbọ́ iwaasu rẹ̀, a sọ nipa wọn pe, wọn "kò si mọ̀ titi omi fi de, ti o gbá gbogbo wọn lọ." Wọnyii ki i ṣe ọrọ lasan. "Ẹniti o ba li eti lati fi gbọ́, ki o gbọ́."

Awọn iyọnu wọnyii yoo ri bi a ti kọ wọn. Bi awọn iyọnu ti Ọlọrun rán si awọn ará Egipti ni akoko Mose ti ṣẹ, bẹẹ gẹgẹ ni awọn wọnyii yoo ṣẹ pẹlu. A o fi egbò dá awọn ti o ni ami ẹranko nì loro; a o sọ okun di ẹjẹ, gbogbo nnkan inu okun yoo si kú; odo ati orisun awọn omi yoo di ẹjẹ patapata, eyi ni pe nibikibi ti o yẹ ki omi ti jade ẹjẹ ni yoo maa jade dipo omi. Oorùn yoo gbona to bẹẹ ti yoo maa fi iná jó awọn eniyan lara, sibẹ wọn kò ni ronupiwada. Igba buburu yii n bọ̀ si adugbo yii, ani nibi ti iwọ ati emi n gbé, nitori naa o tọ́ ki gbogbo wa ri i daju pe a wà ni imurasilẹ fun bibọ̀ Jesu ki a le fi wa pamọ pẹlu Rẹ̀ si ibi Ase-Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan, nigba ti Ipọnju Nla yoo wà lori ayé.

Nigba ti a ṣe akiyesi awọn edidi meje nì ati iro awọn ipe meje ni ati itujade awọn igo meje naa a ri i pe n ṣe ni iyọnu naa n peleke si i bi ọ̀kan ti n pari ti ekeji si n tẹle e. Awọn igo meje naa ni igbi idajọ ikẹyin ti Ọlọrun yoo rán. Nigba ti wọn ba tilẹ dé gongo imuna wọn, awọn eniyan ki yoo yi pada si Ọlọrun; kaka bẹẹ wọn yoo sé ọkàn wọn le wọn yoo si sọrọ odi si Ọlọrun nitori wahala wọn.

**Awọn Aṣẹgun**

Ninu ìran Johannu o ri ẹgbẹ́ awọn eniyan kan ni Ọrun ti wọn n yọ̀ niwaju Ọlọrun pẹlu duru Ọlọrun. Wọn n kọ orin ti Mose ati ti Ọdọ-Agutan. Wọn n yin Ọlọrun fun idasilẹ Rẹ̀ kuro lọwọ Aṣodisi-kristi ati kuro ninu awọn nnkan buburu ti o ti ṣẹlẹ ninu ayé. O dabi ẹni pe isopọ kan wà laaarin orin meji wọnyii. Orin Mose ni eyi ti awọn Ọmọ Israẹli kọ bi a ti n dá wọn silẹ kuro ninu wahala wọn ni Egipti, a si tun n kọ orin naa nisisiyii, pẹlu orin ti Ọdọ-Agutan. Iru orin iyanu wo ni eyi yoo jẹ́! Eyi dabi ẹni pe o n tọka si pe awọn ẹgbẹ́ yii "ti nwọn ti ṣẹgun ẹranko na, ati aworan rẹ̀ ati ami rẹ̀ ati iye orukọ rẹ̀", ti wọn si duro lori okun digi, pẹlu duru Ọlọrun, jẹ́ awọn Ju. O daju ṣa pe a kò le lo ẹsẹ Iwe Mimọ́ yii lati sọ pe ireti igbala wà fun awọn ti wọn wà labẹ itanṣan imọlẹ Ihinrere Arọkuro Ojo ti wọn si kuna ni akoko Ipalarada. Awọn eniyan wà ti yoo ṣe oloootọ ti wọn yoo si fi ẹmi wọn lelẹ nitori ẹri wọn dipo ki wọn gba ami ẹranko ni; ṣugbọn iwọ ti n ka Ẹkọ Bibeli wọnyii ti o si n gbọ́ nnkan ti a n kọ́, ireti rẹ lati ri Ọlọrun pẹlu alaafia ni lati ri i daju pe o ṣe tán lati bá Oluwa lọ nigba ti O ba de ni awọsanma fun Iyawo Rẹ̀. Igbasoke Ijọ le ṣẹlẹ nigbakuugba yoo si ṣẹlẹ dandan ki eyi ti o le pupọ ninu Ipọnju Nla yii to de ba ayé.

**Idajọ Ododo**

Lẹyin ti Ọlọrun ti ṣe ipese fun irapada eniyan, O jare patapata nigba ti O n dá araye lẹjọ fun kikọ ọ. Awọn ẹlomiran le maa ro pe Ọlọrun alaaanu ko ni rán idajọ bẹẹ sori awọn ti n gbé ori ilẹ ayé. Ṣugbọn abayọrisi rẹ̀ ni pe awọn funra wọn ni o beere rẹ̀, nigba ti wọn kọ ipe aanu Rẹ̀, ti wọn si kuna lati mu anfaani ti O pese silẹ fun wọn lò lati sá là kuro ninu ohun ti O sọ fun wa pe o n bọ̀. Wolii Isaiah fun ni ni ikilọ o si n tọka si ipese naa ninu Isaiah 26:20, 21: "Wá, enia mi, wọ̀ inu iyẹ̀wu rẹ lọ, si se ilẹkun rẹ mọ ara rẹ: fi ara rẹ pamọ bi ẹnipe ni iṣẹ́ju kan, titi ibinu na fi rekọja. Nitorina, kiye si i, OLUWA ti ipò rẹ̀ jade lati bẹ̀ aiṣedede ẹniti ngbe ori ilẹ wo lori ilẹ; ilẹ pẹlu yio fi ẹ̀jẹ rẹ̀ hàn, kì yio si bò okú rẹ̀ mọ."

Eyi n sọ gbangba-gbangbà pe o ṣe e ṣe lati là. O n sọ fun wa pe a le ni anfaani ki a sé wa mọ́ pẹlu Oluwa ni akoko Ajinde Kin-in-ni. (A o sọ ti anfaani awọn ti a gbà soke ninu ẹkọ ti n bọ̀). Ṣugbọn nigba ti a ba n tú awọn igo idajọ wọnyii jade, awọn ti o kù nihin ni a o fi nnkan ti kò ti si ri, ti ki yoo si tun si lẹyin naa, jẹ ni iyà.

**Ogo Ọlọrun**

Eefin ti o kún Tẹmpili ni Ọrun ati Ogo Ọlọrun ti Johannu ri nibẹ n rán wa leti iran ti o ṣipaya nigba ti a ya Tẹmpili Sọlomọni si mimọ́. Ọkọọkan ninu akoko meji yii n fi ifẹ Ọlọrun hàn ninu igboke-gbodo ọmọ eniyan. O n dẹ eti Rẹ̀ silẹ, O si n bukun awọn eniyan nigba ti wọn ba n sin In ni otitọ ti wọn ba si n gbé orukọ Rẹ̀ ga. O n dẹ eti Rẹ̀ silẹ nigba ti awọn eniyan ba n tapa ti wọn si kọ̀ lati gbọran si I lẹnu; nigba ti a ba si rán idajọ jade, fun Ogo Ọlọrun ni eyi naa jẹ pẹlu. Ọlọrun jẹ́ Ọlọrun alaaanu, ṣugbọn ko le jẹ́ olododo bi a ko ba dá ẹ̀ṣẹ lẹjọ. A ki i rán idajọ lai jẹ pe a ba kọ́ fi aanu lọ eniyan.

Ni Ọrun angẹli naa wi pe, "Olododo ni Iwọ, Ẹni-Mimọ́, ẹniti o mbẹ, ti o si ti wà, nitoriti iwọ ṣe idajọ bayi." Nigba ti Kristi wà ninu ayé, O fi paṣan lé awọn onipaṣipaarọ owó jade kuro ninu Tẹmpili, nitori wọn ti sọ ile Oluwa di iho ọlọṣa. Bẹẹ gẹgẹ ni ibinu Ọlọrun ti a o tú jade ni igba ipọnju ti n bọ̀ yoo jẹ fun ogo Rẹ̀, gbogbo awọn ẹni irapada lati ọjọ iwa wá ni yoo yọ̀ pẹlu Rẹ̀ ninu idajọ wọnyii – ki i ṣe nitori a jẹ awọn eniyan ni iyà ṣugbọn nitori ododo ni idajọ Ọlọrun.

**Ipọnju Sibẹsibẹ Lai Si Ironupiwada**

Awọn miiran le wi pe nigba ti wahala nla naa ba de awọn yoo ronupiwada, awọn yoo si wá Ọlọrun. Ṣugbọn nigba ti oorun gbona to bẹẹ gẹẹ ti ooru nla fi n jó awọn eniyan, wọn n sọ ọrọ-odi si orukọ Ọlọrun, wọn

kò si ronupiwada. Ironupiwada ki i wá nipasẹ wahala nikan bi ko ṣe nipa sisọji òye eniyan lati ọwọ́ Ẹmi Mimọ́. Nigba ti a ba fi ẹ̀ṣẹ han ni bi o ti buru to, ẹlẹṣẹ a ri i pe irira ni ẹ̀ṣẹ oun jẹ́ ati pe ọkàn oun yoo wà ni idalẹbi ayafi bi oun ba ke pe Ọlọrun fun aanu pẹlu ironupiwada tootọ. Awọn miiran le dé iru ipo yii nipa wahala, ṣugbọn ọpọlọpọ ninu awọn ti wọn ni wahala wuwo ni wọn wà ninu ewu ati gbagbe Ọlọrun ni akoko wahala naa, nitori wahala naa yoo ti gba ọkàn wọn kan. Bakan naa ni iṣẹ ami ati iṣẹ iyanu ki i saba mú eniyan ronupiwada. Baba Abrahamu wi fun ọlọrọ nì ti o wà ni ọrun apaadi pe bi awọn arakunrin rẹ̀ marun-un ko ba gba Mose ati awọn woli gbọ́, wọn kò ni gbagbọ́ bi ẹni kan tilẹ dide lati inu oku lọ ba wọn.

**Ipari**

Bi a ti n tú igo ikẹyin jade a gbọ ọrọ wọnyi: "O pari." Wọn ti sọ ọ pe, "Eyi n sọ fun wa taara lati ibi itẹ idajọ funra rẹ̀ pe nihin yii ni a gbé de opin, ati pe pẹlu itujade yii gbogbo ẹkunrẹrẹ ibinu Ọlọrun lori ayé yii pari." Ninu ogun Harmagẹddoni, ninu eyi ti awọn ọba ati awọn ogun ayé gba ara wọn jọ si Kristi ati ogun Rẹ̀, nibẹ ni a o ti ṣẹgun awọn agbara buburu wọnyii ti a o fi ifihan wiwá Rẹ̀ pa. Awọn ti a kò parun ni a o mú wa si itẹriba ati igbọran labẹ iṣakoso Kristi, nitori nigba naa ni yoo gbé Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun kalẹ lori ayé yii.

Ọpọlọpọ iṣẹlẹ ni yoo ṣẹlẹ ni igba ifihan Kristi. Lẹyin ti wọn ba ti ni ipin ninu Ase-Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan, anfaani giga ti awọn ẹni-irapada nì ni lati bá Kristi pada lori ẹṣin funfun ati lati bá A ṣe akoso ati ijọba fun ẹgbẹrun ọdun.

**AWỌN IBEERE**

1 Lori ta ni awọn aṣẹgun inu ẹkọ yii ti gba iṣẹgun?
2 Eredi orin Mose?
3 Ki ni jọ ara wọn laaarin orin ti Mose ati orin ti Ọdọ-Agutan?
4 Nibo ni Johannu kọkọ ri iran yii ninu iṣipaya?
5 Ki ni a le fi wé ara wọn laaarin awọn ohun ti o ṣẹlẹ ninu Tẹmpili ni Ọrun ati ninu Tẹmpili Sọlomọni ni akoko iyasimimọ́ rẹ̀?
6 O ha sọ awọn odo di ẹ̀jẹ ni tootọ? Wọn ti ri bẹẹ ri bi?
7 Nigba wo ni a o ja ogun Har-magẹddoni?
8 Nibo ni awọn ogun Ọlọrun yoo ti wá?